**OWE**

IRETI awon agabagebe asa ni nja si. Eniti o ba yo ile ara re l'nu yio jogun ofo.

Asiwere ni yio ma a se iranse fun Ologbon.

# Irohin Yoruba

No 807 NOVEMBER 23 — NOVEMBER 29, 1960 KOBO MEJI (2D)




# OSADEBAY DI ALAKOSO IGBIMỌ AGBA OṢELU

## Ọba Adeniji Adele wa bakanna





AWORAN oke yi lowo otun ni ti Oloye Dennis Osadebay, Alaga titun ti Igbimo awon Oselu-Agba. Aworan owo osi l'oke yi ni ti Oba Adeniji Adele Keji ti o wa ni aye Igbakeji Alaga Igbimo na, eyiti o ti wa tele-tele. Aworan egbe odun yi ni ti igbati Olola Dokita Nnamdi Azikiwe nki Oloye Obafemi Awolowo, Olori Egbe Afenifere ati asiwaju Egbe Alatako ninu Igbimo awon Asofin Apapo Ijoba Naijiria l'ojo ti awon nfi Olola Dokita Azikiwe je oye Gomina-Agba Apapo Ijoba Naijiria ni gbangba odan l'Eko. Wo oju ewe kejila fun irohin ati aworan yoku.

**ATỌKA Wo**

Alapara Ibadan —P 2
Itumo Ala——P 8
Akibu Alarape——P 9
Akiyesi Awon Awo-awo nipa ojo'bi P 11

# Awolọwọ ki Azikiwe ku-orire oye Gomina-Agba ti o jẹ

WỌNYI ni ọrọ inu iwe ti Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Olori Apapọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Aṣiwaju Ẹgbẹ Alatako Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria kọ ranṣẹ si Ọlọla Dọkita Nnamdi Azikiwe, Gomina-Agba titun, ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi, lati fi ki i ku-orire ipo Gomina-Agba ti o bọ si nigbati o ku ọla ki o gori-oye na. Bayi ni ọrọ inu iwe na lọ:—

Ni ọla ni a o fi ọ jẹ oye Gomina-Agba Apapọ Ijọba Naijiria. Lati ọdun 1941 titi di nkan bi oṣu mẹta sẹhin ni iwọ ati emi ti jẹ orogun paraku ninu iṣẹ-iṣelu. Ṣugbọn o yẹ ki nṣe alaye rẹ dada pe, bi o ti wu ki o ri, lori ọran ilu nikan ni ero temi tirẹ fi yapa si ara wọn, a ko si fi igbakan doju ija kọ ara wa ri nitori ọran ti ara-wa-si-ara-wa. Bẹni, bi o ti ga to, ti o si lagbara to ninu iṣẹ-iṣelu, mo ti fi gbogbo agbara mi ba ọ jijakadi, sibẹsibẹ, gẹgẹbi ẹda, nko fi igbakan ro buburu si ọ ri.

**OJỌ NLA**

"Ni nkan bi oṣu mẹta sẹhin ni o ti bọ aṣọ ija iṣẹ-iṣelu silẹ lati mura silẹ de alomanigbagbe ọjọ nla ti o nduro de ọ lọla. Lati igbana ni mo si ti nkiyesi ọrọ ẹnu rẹ, o si tẹ mi lọrun wipe, o ti ngbiyanju lati ṣe ipalẹmọ ọkan rẹ dada ki o le jẹki o ṣe iṣẹ ilu Naijiria dada gẹgẹbi o ti yẹ fun ẹnikẹni ti o ba bọsi iru ipo titun bẹ ẹ.

"Mo ti nfi igbakan ṣe atako ero pe ki o jẹ oye Gomina-Agba na, ṣugbọn ni ọna iṣẹ-iṣelu nikan ni. Mo mọ daju gbangba, gẹgẹbi mo ti mọ titi di isisiyi pe, o ni ẹtọ lati bọ si ipo giga yi gẹgẹbi ẹnikẹni ni Naijiria ti ni ẹtọ si i. Ṣugbọn mo ti ni ero wipe, ẹni bi irẹ, ti o ti wa ninu iṣẹ -iṣelu paraku fun ọjọ pipẹ, ati gẹgẹbi ọjọ ori rẹ (ti o fi nkan bi ọdun mẹrin tayọ temi) yio jẹ inira fun un lati yi ara rẹ pada kuro ni ọna akikanju alatilẹhin ẹgbẹ-oṣelu ti o wa si ipo Gomina-Agba. Gẹgẹbi awọn ọrọ ẹnu rẹ ati ihuwasi rẹ larin ọsẹ diẹ sẹhin, o ti fihan gbangba pe o le ko ara rẹ ni ijanu gẹgẹbi aye iṣẹ rẹ ti nfẹ ati gẹgẹbi o ti jẹ ọranyan fun ọ lati pa ofin Ijọba wa mọ.

"Nwọn ti sọ wipe, Ọba ti o ṣe aṣoju rẹ, ti o si npaṣẹ labẹ adehun ofin Ijọba Ilẹ wa lati ṣe afarawe rẹ ni gbogbo ọna, jẹ ọba ni, ki i paṣẹ. Ṣugbọn, sibẹsibẹ, ọla nla ni lati jẹ oye yi titi di igbakigba lori ilu nla bayi, ogunlọgọ awọn enia ati ọrọ ainipẹkun ilẹ Naijiria.

**IṢẸ GOMINA-AGBA**

"Iṣẹ rẹ gẹgẹbi ofin, ni lati fi imọran ati ikilọ si iwaju Alakoso Apapọ Ijọba ati awọn Minisita Apapọ Ijọba ni aṣiri. O tọ fun wọn lati gba ki nwọn si pa a mọ tabi ki nwọn si kọ iru imọran bẹ ẹ ti o ba fẹ fun wọn. Ṣugbọn o ye mi lati gbagbọ pe, iru imọran tabi ikilọ ti o ba fun wọn yio jẹ eyiti o wuwo ti o si yi enia lọkan pada gidigidi, gẹgẹ bi agbara imọ-ijinlẹ rẹ, ati gẹgẹbi oye rẹ ati iduro gbajumọ rẹ ni igboro ilu tabi ilẹ wa. Nitori idi eyi, mo ni ireti wipe, imọran-kimọran ti o ba gba, ko ni ni inunibini tabi ojusaju ninu, yio si jẹ imọran fun ilọsiwaju ati ifaramọra gbogbo apapọ ilẹ Naijiria ati fun alafia ati itẹsiwaju ati ifaiyabalẹ gbogbo awọn enia wa.

"Ni orukọ ẹgbẹ oṣelu mi ati emi tikala ara mi, mo fi ọwọ sọlya fun ọ pe, a ki yio gbiyanju lati fẹjuawọn lati mọ ohun ti o ti sọ tabi ti o ko ti i sọ fun awọn Minista rẹ. Ani, ọrọ ti o ba tilẹ sọ ni gbangba ni a o ka si gẹgẹbi ilana ati eto Apapọ Ijọba Naijiria, bẹ ẹ gẹgẹ ni ao si ṣe sọrọ nipa rẹ, ayafi bi Alakoso Apapọ Ijọba ba kọ ọ tabi ti ko ba fi ara mọ ọ patapata. Nitori idi eyi gan an, Ẹgbẹ Afẹnifẹre

(Wo oju ewe kẹwa)



**DOKITA AZIKIWE**
Gomina-Agba Apapọ Ijọba Naijiria.


# Da Ikọ Otutu Duro

Ti o ba nwukọ tabi o ngmi tipatipa ti o ko si le mi delẹ tabi sun dada nitori ikọ-ife tabi amodi imu tabi ikọ-otutu ti o nba ọ ja, lọ ra MENDACO loni ni ile itaja-agbogi. MENDACO ma a nṣiṣẹ ninu ẹjẹ ati iho ọna ọfun lati yọ gbogbo kẹlẹbẹ ti o ba di sibẹ. Nigbana ikọ rẹ a fuyẹ, wa a si le mi dada, wa a si ma a sun bi ọmọ-ọwọ, wa gba agbara rẹ gan an pada. Bi ko ba jẹ bẹ ẹ, a ṣe ileri lati da owo rẹ pada. Lọ ra MENDACO loni lọdọ onibara rẹ ti o nta oogun.

Kọ gbogbo awọn adamọdi silẹ!
Oiulowo kanṣoṣo
MENTHOLATUM
ni o wa

Ninu awọn idẹ ati agolo bawọnyi ni a nta wọn




Lati ọdun 1890 ni a ti nta a bakiri gbogbo agbaiye.

FI OJU WA AMI-IṢOWO
MENTHOLATUM
IPARA TI O DARA JU GBOGBO IPARA LỌ

O le bẹrẹ si fi iwọn iba owo kekere bi ṣile marun 5/- pamọ si ọdọ ...



BRITISH & FRENCH BANK LTD.
Branches in Nigeria LAGOS, LAGOS EAST, APAPA, EBUTE METTA, IBADAN, PORT HARCOURT, KANO, KADUNA

IṢẸ KIAKIA | ERE DADA | GBIGBAPADA NI IRỌRUN | AABO TI O DAJU

# Ijọ Ẹgbẹ Mimọ ṣe ajọdun l'ori Oke Igboho

NI ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kẹtadinlogbọn osu kẹwa ọdun yi ni ẹsẹ gbogbo awọn ọmọ Ijọ Ẹgbẹ Mimọ Kerubu ati Serafu lati igun mẹrẹrin agbaiye ti pesẹ si ilu Igboho lati gun ori oke fun akanṣe adura ọdọdun ti nwọn ma nlọ ṣe. Nigbati o di agogo mẹrin irọlẹ ọjọ na ni Baba Aladura, Prophet J. O. Adeọla, aṣoju ati oludasilẹ ori oke na, de sinu Ile Adura, lẹhin ikilọ fun gbogbo enia nipa aṣẹ Oluwa, nwọn kọ orin, nwọn si gbadura, lẹhinna, ni nwọn to lẹsẹ-ẹsẹ ti nwọn si nlọ gun ori oke na pẹlu orin, ilu ati ijo, gbogbo awọn ara ilu lo nwa to si ẹgbẹ oju ọna, ti Baba Aladura si ngbadura fun wọn bi o ti nlọ, ẹyẹ ati ariya ọjọ na po, o si dun jọjọ.

Nigbati nwọn de ori oke na ni ago mẹfa irọlẹ, nwọn ṣe isin, nwọn si gbadura fun gbogbo orilẹ-ede paapa fun ilẹ Naijiria ti o ṣẹṣẹ gba ominira. Lẹhinna ni gbogbo awọn ti o wa ninu awẹ lati owurọ ṣẹṣẹ lọ jẹun ni ago meje alẹ ọjọ na. Iye awọn enia ti o gun ori oke na jẹ ẹgbẹrun enia o le adọta (1,050). Ni ago mẹsan alẹ ni nwọn ti bẹrẹ orin, ati adura titi di ago kan oru. Ni ago marun idaji ni nwọn ti tun bẹrẹ isin titi di agogo mọkanla owurọ, ninu Isin akoko yi ni Oluwa ti bẹrẹ si ba wọn sọrọ nipa awọn ariran ati awọn ẹlẹmi. Iyanu ni eyi jẹ fun awọn ti ko ti ri iru nkan bẹẹ ri, awọn ti ki iṣe Ijọ Aladura ti nwọn wa si ori oke na, Oluwa fi ibere wọn han fun wọn, inu gbogbo enia si dun pupọ pe Ọlọrun ngbe arin awa enia sibẹ.

Alagba George Okutoro lati Ifọ ni o ṣe iwasu lori oke na. Iwasu na larinrin pupọ, o si kọ wa lẹkọ ninu ọrọ Ọlọrun.

Ohun gbogbo nlọ dada lori oke na, awọn Kerubu (ọlọpa aladura) nwọn nyi ori oke na po lati si i pe ko si ija tabi idamu fun ẹnikẹni, nwọn si nbu omi fun awọn enia lati inu odo ti o wa larin apata lori oke na fun mimu, ati fun wiwẹ awọn ọmọde.

Ni owurọ ọjọ kẹta lori oke, gbogbo awọn ti Oluwa ṣe l'ore, ati awọn ti nwọn jẹ ẹjẹ, nwọn nwa fi ore Ọlọrun han, nwọn si nsan ẹjẹ wọn, ti gbogbo wọn si nho fun ayọ ati orin didun. Awọn ẹgbẹ akọrin lati orori ilu si bẹrẹsi kọrin aladun, paapa awọn akọrin ẹgbẹ ilu Igboho, nwọn fi orin dabira lori oke na, ti a ko le rohin tan ninu iwe yi.

Ni dede agogo meji ọsan ọjọ Satide 29-10-60 ni nwọn sọkalẹ lori oke na. Awọn ọdẹ ko ibọn wa pade wọn fun ajọyọ, nwọn si ngyin ibọn, awọn ọdẹ na jẹ ọgọrun o le marun. Lẹhinna ni ọpọlọpọ awọn enia ara ilu tun wa pade wọn, ti gbogbo wọn si jọ jo titi de Ile Adura wọn, ti nwọn si gbadura ọpẹ si Ọlọrun, ki olukuluku to lọ si ile wọn, nwọn si fi awọn alejo wọ si ibiti a ti pese silẹ fun wọn.

Ni ọjọ Aiku ti iṣe ọgbọnjọ oṣu kẹwa ọdun yi, nwọn ṣe isin owurọ ni agogo mẹsan si mejila. B. A. Ajagbe ni o ka Ẹkọ kini, Prophet David Oyetola Ogbomọshọ ni o ka Ẹkọ keji. Baba Fiditi, Gabriel



Prophet J. O. Adeọla

* * *

Adeleke ni o ṣe iwasu lori igberaga pe ko dara, iwasu na larinrin pupọ, lẹhin isin na, Baba Aladura J. O. Adeọla ṣe oreọfẹ.

Ni agogo mẹrin irọlẹ ọjọ isimi na ni gbogbo wọn lọ sode larin ilu fun iwasu ode gbangba. Evangelist J. J. Akande Ogbomọshọ ni Oniwasu na, ọpọlọpọ awọn enia ti nwọn ti gburo Evangelist na ti nwọn si fẹ lati mọ ọ, ati lati gbọ iwasu rẹ, gbogbo wọn lo wa sibẹ, enia pọ pupọ tobẹ ti a ko le ka iye wọn ilu Igboho mi titi lọjọ na, irohin ko to afojuba. Akande ṣe alaye gẹgẹ bi a ti ṣe le wa ni alafia larin ara wa l'aiye yi, ati gẹgẹbi a ti ṣe le wọ Ijọba Ọlọrun nipa igbagbọ ninu Jesu Kristi. Iwasu ọjọ na wọ gbogbo enia l'ara, bi o ti ntọka si Bibeli bẹni o si ntọka si Alkurani ti o si nkewu.

Gbogbo awọn Imale paapa farabalẹ dada gbọ iwasu na. Awọn diẹ ninu awọn aṣaju Imale ti nwọn yọju fun atako, gbogbo won ni nwọn di alairiwi niwaju Akande, ọkan ninu won jẹwọ gbangba pe o gba pe otitọ ni ọrọ ti Evangelist Akande sọ ọna meji ni nwọn gbe duro ṣe iwasu lọjọ na, nwọn si dari sile ni agogo mọkanla oru ọjọ na.

Ni owurọ ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kọkandilogbọn oṣu ti o koja na ni ọpọlọpọ ti bẹrẹsi pada lọ si ilu wọn, awọn miran duro fun ipade committee, Baba Aladura J. O. Adeọla si lọ ṣe itẹbọmi (baptism) fun ọpọlọpọ awọn ti o nfẹ.

Awọn ti o wa si ori oke na niwọnyi:—Evangelist J. J. Akande, Prophet D. Oyetọla, Michael Igbalajọbi, lati Ogbomọshọ. Woli Daniel Afọlabi, Leader Moses Ọladọtun, Jeremiah Awoleyẹ, lati Ifẹ Ọdan, ati Thomas Adedokun, George Okutoro Ifọ. Ogunbiyi Alaga, David Ọlaoye, B. A. Ajagbe, S. Eyinade, E. Ladokun, Josiah Akande, Gabriel Adeleke, John Ishọla, Samuel Labọde, Daniel, Woli Jacob Oyesiji, ati ọpọlọpọ awọn enia ti a ko le darukọ tan sihin.

Ni gbogbo ọjọ kẹtadinlọgbọn oṣu kẹwa ọdọdun ni ao ma gun ori oke lagbara Oluwa.

Aṣeyi ṣ'amọdun o.

Ẹ ma a polowo ọja nyin sinu iwe "Irohin Yoruba"




# ẸGBẸ ỌMỌ ODUDUWA ṢE AJỌDUN KẸTALA ALARINRIN NI IBADAN






* *



## Ijọ Serafu fẹ ṣe ajọdun ikore

## Ran awọn eree lọwọ Da ẹhin didun duro

Cystex


O KURO NINU ERE-IJE ?

Taji loju oorun Ki o si ṣ'ara giri !

Pẹlu

ANDREWS LIVER SALT



ANDREWS

LIVER SALT


## CLASSIFIED ADVERTISEMENTS

# ITUMỌ ALA

**Lati ọwọ Josẹfu Alala, Mushin**

AGBOORUN—Ti o ba la ala pe o wa ni abẹ agboorun, iṣipo pada tabi ati ile de ile yio wa fun ọ.

FILA—Fila didẹ loju ala ko dara, ti o ba nfẹ iyawo laseko yi, ko ni bọ si, ti o ba si mu lọwọ tabi ti atẹgun ba re bọ ni ori rẹ, ṣọra gidigidi maṣe ba enia pa apabo ohun buburu nitoripe aṣiri yio tu.

IGBEKUN—Ti o ba la ala pe nwọn mu ọ ni igbekun tabi o ri awọn ti nwọn mu ni igbekun, ṣọra gidigidi ki o ma ba a sọ owo ti yio ka o lara nu tabi ni idakeji ọwọ ki o ma ba a fi ibinu da ọran.

MỌTO-AYỌKẸLẸ—Bi o ba la ala pe o wa ninu moto ayọkẹlẹ, ikilọ ni itumọ ala yi, ṣọra nipa jamba airotẹlẹ ki o ba le fo ọ ru.

ẸNI—Ti o ba sun le ẹni loju ala tabi o ntẹ ẹni, o dara pupọ iwọ yio jere pupọ ninu ọja rẹ, ti o ki ba si i ṣe oniṣowo iwọ yio ri enia ti yio fi owo ta ọ lorẹ.

KẸKẸ ẸLẸṢIN—Ti o ba la ala pe o wa ninu kẹkẹ ti ẹṣin nfa, ko dara rara, ṣọra nipa adunrunmọ ti o le jẹki Ijọba jẹ ọ ni ọkọtọ iya.

GBẸNAGBẸNA—Ti o ba ngbẹ ere loju ala, tabi o ri ẹniti o ngbẹ ere, ala dada ni, iwọ ko ni pẹ jogun ohun alumọni kan tabi ki o ri nkan olowo iyebiye he.

ANGẸLI—Ti o ba ri awọn Angẹli loju ala, ma a yọ ala rere ni, iwọ ko ni ni ibanujẹ.

EERA—Ti o ba ri awọn eera loju ala, ti o ba jẹ oniṣowo, iwọ yio ma ri ere pupọ jẹ lori iṣẹ rẹ laseko na, ti o ba si ṣe oṣiṣẹ ti o ngba owo oṣu, igbega yio wa fun ọ nibi iṣẹ rẹ laseko na.

Bere itumọ ala rẹ lọwọ Josẹfu Alala, Elephant House, 214, Broad Street, Lagos.





## Itan Ti Julius Sọ Lori Ọti Waini Ti O Nfunni Ni Ilera

*Ẹ Ka nkan ti ọẹl Atẹjẹṣẹ* PHOSFERINE TONIC WINE *ṣe fun Julius Ajayi ti ongbe, 8, Akintoye Street, Yaba, Lagos.*





Lọ Si Sọbu Ibiti O Ti Nra Ọja Kiakia ki O Si Ra Ọti Waini Atẹjẹṣẹ, PHOSFERINE TONIC WINE Fun Ara Rẹ

*Maṣe gbagbe lati yi ẹrọ asọrọ magbesi rẹ (Radio) si si ibiti O ti le gbọ "Famous Fortunes", awọn itan ti wọn sọ ki a ti le ri iyege ninu gbogbo nkan ti aba mọ.*

*✻ Kọwe si Phosferine Tonic Wine, P.O. Box 431, Lagos fun iwe kekere ni ti O sọ bi O ti le ni ilera.*

# Ori lo mọsẹ asela ẹni

(Lati oju ewe kẹsan)

Sugbọn gbogbo bi iyawo kekere yi ti nṣe ni ọmọdekunrin ti o sapamọ si ori aja na nṣe akiyesi rẹ lẹsẹ-ẹsẹ, ati pe, bi iyawo kekere yi ti nfi ado na le ori aja, ọwọ ọmọdekunrin yi yio bọ si, o nyta rakoro lọ sibẹ, o si mu u pamọ sinu apo-ẹwu rẹ. Laipẹ lẹhin eyi, Ọba dari wọle lati apejọ awọn ọpọlọpọ enia ja-nkan ja-nkan. Nigbati nwọn ba Ọba dele tan, olukaluku si pada lọ si ile rẹ gẹgẹbi iṣe wọn.

Lẹhin na ni Ọba paapa wa bọrasilẹ lati jẹun pẹlu iyawo rẹ, iyawo kekere yi si ti tọju onjẹ tiwọn si aye ibiti nwọn yio ti jẹun. Bayi ni Ọba ati iyawo rẹ ba wẹ ọwọ wọn lati jẹun, nje ki nwọn bẹrẹsi jẹun ni nwọn gbọ ariwo nla kan lati ori-aja wipe: Ewọ, ewọ, ewọ, ẹ ko gbọdọ fi ọwọ kan onjẹ ngni rara, bibẹẹkọ loni ni ẹnyin mejeji yio fi aiye silẹ ti ẹ o si di ero ọrun alakeji!

Enu ya Ọba pupọ lati gbọ ọrọ yi, ẹru nla si ba iyawo Ọba ti on ati Ọba nfẹ jijọ jẹun na to bẹ ẹ ti o fi ṣubu lulẹ lati ori ijoko. Lẹsẹkẹsẹ ni ọmọdekunrin ti o kigbe lati ori-aja na bẹ silẹ lati ori aja, o gbe iyawo Ọba na dide pada si ori ijoko rẹ, o si di Ọba ati iyawo rẹ ni ọrun ọwọ mu ṣin-ṣin-ṣin, o nsọ fun wọn wipe, onjẹ yi ki i ṣe jijẹ fun nyin rara, bi ẹ ba fi ẹnu kan an, ẹ o ku loni ki ilẹ to ṣu, ko si tabi-tabi nibẹ.

Ọrọ yi sa jẹ iyalẹnu nla fun Ọba na ni, to bẹ ẹ ti ko tilẹ mọ ohun ti o le sọ rara mọ, o sa nwo ọmọdekunrin na pẹlu iyanu nla ni, o si bẹrẹsi sọ wipe: "Ha! ha!! Tani eleyi?" Olotu, a dupẹ o, ipade tun di ọjọ miran ọjọ rere o, o digba.




AMAMA nfun ni ni agbara

Manufactured by Glaxo Laboratories (Nigeria) Ltd., Apapa.
Trade enquiries: Glaxo-Allenburys (Nigeria) Ltd., Lagos, Aba and Kano

# Awolọwọ ki Azikiwe ku-orire

(Lati oju ewe kẹta)

yio dari ibọn ija rẹ kuro ni ọdọ rẹ patapata lati igba yi lọ; sugbọn yio koju ija rẹ si Apapọ Ijọba Naijiria lori iṣẹ Apapọ Ijọba Naijiria ati; lori iṣẹ Ijọba Ipinlẹ, si awọn ẹgbẹ-oṣelu ti o ba nṣe alatako wa.

"Ni orukọ gbogbo awọn Aṣiwaju Ẹgbẹ Afẹnifẹre ti Naijiria ati ti iyawo mi ati emi paapa, mo fi tọkantọkan ki ọ ku orire ati iyawo rẹ, Iyaafin Azikiwe. Mo fi tifẹ-tifẹ gbadura pe ki Ọlọrun fun nyin ni alafia ati ilera ati ire gbogbo inu Ile-iṣẹ nyin titun. Mo si gbadura tọkan-tọkan pe ki o wu Ọlọrun Olodumare pe ki o dari okan rẹ, ki o si ṣe akoso rẹ si ọna rere, ki o si jẹki akoko iṣẹ rẹ jẹ ti igbega ati ibukun fun gbogbo awọn enia wa, ati apẹrẹ rere fun gbogbo awọn enia ti yio ba tun bọ si ipo na lẹhin tirẹ.

"Mo fi gbogbo ara mi ati ọkan mi ki ọ ku-orire, ki Ọlọrun ṣe gbogbo ọna rẹ ni rere."

## Akiyesi pataki



EYI ni lati sọ fun gbogbo ẹnyin ara ilu agbegbe Kadjevbi, Ghana, ti o ba fẹ iwe Irohin Yoruba ki o lọ si ọdọ Ogbẹni Karimu Adeyẹmi ti aworan rẹ wa loke yi. On ni aṣoju wa ni ilu Kadjevbi, Ghana

OLOTU

*Ẹ ma a ka Iwe*
***IROHIN YORUBA***
*nigbagbogbo fun irohin aladun*



DA

INU-RIRUN DURO

Nigbati o ba ni irora ninu ikun rẹ, ohun ti o nfa idi rẹ nigbagbogbo ni pe omiro ti pọju nibẹ. Omiro yi ni o nfa arun-inu, inu-kikan-ni ati airi-igbẹ-ya.
Ṣa ti mu egbogi Phillip's 'Milk of Magnesia' diẹ .........yio si ko rirogun omiro na kuro, a si le irora na lọ werewere. Yio fun okun-inu lagbara lati ti gbogbo nkan ti o nfa irora na jade kuro lara.
Ko lewu, o rọrun lati lo, o si tu ni lara,

'MILK OF MAGNESIA'

Awọn ti o nṣe e ni

PHILLIPS

ODARA FUN GBOGBO ẸBI



# Osadebay di Alaga Igbimọ awọn Agba Oṣelu

## Adajọ sọ Ade Bello s'ẹwọn

IBADAN.

ADAJỌ so Ade Bello, Gbakeji Olori Eka Ẹgbẹ Alakukọ NCNC Ibadan si ẹwọn oṣu mẹfa ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu yi fun jijẹbi ti o jẹbi ẹsun ole, ọgọrun pọnun.

Bi ẹjọ na ti ri ni pe Lasisi Ayantọla ọkan ninu ọmọ Ẹgbẹ Alakukọ fi ọgọrun pọnun ran Bello pe ki o ba on mu fun Alamojuto Ẹgbẹ Alakukọ ni Eko fun owo-idogo lati fi orukọ silẹ fun yiyan, dibo wọ Ile Igbimọ Apapọ Naijiria ni Bello ba fi owo na gbọ ti ara rẹ, ni o ba di ẹjọ.

LAKUREGBE!
ALGESAL
ti le e lọ

ALGESAL jẹ ilọsiwaju iyanu fun igbogunti Lakuregbe. O dara ju ti atẹhinwa lọ. On pa oro pajapa. ja ati ara riro. ALGESAL ni DITYLAT ninu, aṣẹṣẹwakan apore titun ti nwọnu isan ara lọ, a si ma a yara tuka sinu ẹjẹ. ALGESAL tura o si nṣe iwosan kiakia, o ndi iwura ku. Sa fi pa a, gbogbo irora ati iwora Lakuregbe ni yio si lọ patapata. ALGESAL jẹ iyanu fun ara wiwu pẹlu. Bere ALGESAL kakiri ile-itaja. Ona-ijinlẹ ti nwọn fi dan ALGESAL wo fi han pe, o nwọ inu awọ ara jinlẹ ni igba mẹta ju awọn ogun ipara yoku lọ. ALGESAL ni orun didun, ko si ni abawọn ti i si jọ ara. ALGESAL tura, o si le irora lọ. Ajo rẹ kọọkan nigba enia ni ilera alagbin.

LO ALGESAL FUN
Lakuregbe • Aradidun
Ara Wiwu • Pajapaja
Iwora • Latanlatan
Tutu • Arinka
ALGESAL dara fun awọn ti o nṣere ije pẹlu

D.P.I. Ltd., 1 ... Road, P.M. Bag 1256, Apapa.

Nigbati Igbimọ awọn Oṣelu Agba Apapọ Ijọba Naijiria (Senate) bẹrẹ ipade l'Eko ni ọjọ ọjọbọ ti i ṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi ni Oloye Dennis Osadebay, Aṣ'waju Ẹgbẹ Alatako Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ni nwọn yan ni Alaga Igbimọ na rọpo Ọlọla Dọkita Nnamdi Azikiwe, ti o ti jẹ Alaga na tẹlẹ ri ki o to di Gomina-Agba Apapọ Ijọba Naijiria.

Eyi ya ọpọlọpọ awọn enia ti o wa woran lẹnu, nitoripe Ọba Adele ni Igbakeji Alaga Igbimọ na on si ni gbogbo wọn ti fi ọkan si pe on ni nwọn yio yan ni Alaga rọpo Ọlọla Dọkita Azikiwe.

Ṣiwaju ki nwọn to yan alaga na, Irohin ti kan kakiri Ilu pe Ọba Adele ni yio jẹ alaga, tobẹ ti awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu Ọba na Mabọlajẹ fi nyọ ayọ kakiri ilu. Ṣugbọn ina ireti Ọba ati awọn ọmọ Ẹgbẹ Mabọlajẹ re ku nipa rẹ, Ọba Adele si wa bakanna.

Aworan isalẹ yi ni ti igbati Oloye Rotimi Williams ki Dọtita Banda kuabọ lọjọ ti nwọn nfi Ọlọla Dọkita Azikiwe jẹ Gomina-Agba.



Basikulu agbayanu julọ laiye . . .
RALEIGH 'Superbe'
STURMEY ARCHER

IYATỌ TI O WA FUN RALEIGH "SUPERBE"
O tun ni:—Ọpa idabu pataki ti a fi irin-tutu ṣe ... ṣe iho rẹ, ti a si gbẹrọ dada. Ọpa idimu—oni-"D" ti o ... dada ni iparí rẹ. Kọkọrọ orun basikulu ti o ... Ijoko-gari Brooks. Anfani Isura irinṣẹ Sturmey-Archer. Ọda didan ... ati oṣo irin-funfun ti o dara.
ANFANI AWỌN IṢẸ RALEIGH FUN Ọ
★ Awọn iyara ifojaban ni Mushin, l'Eko ati ni Ile Tito Irinṣẹ Basikulu ni Mushin fifi gbogbo ... Basikulu Raleigh han
★ Iṣẹ tito-pari ati ... irinṣẹ ati ...-atunṣe wa ni Mushin
... ni ọdọ pẹlu Sturmey-Archer Oni-jia bale mẹta ati ina Dynohub. Ayọ nla ni lati ni basikulu Raleigh "Superbe" ki a si ma a gun un. Ko ni afarawe nipa siṣe, didara, agbara ati arẹwa ọda ti nwọn fi ṣe oṣọ rẹ; on ni basikulu ti o peyẹ ni siṣe julọ laiye—ati eyiti o ni eelo-irinṣẹ julọ. A to gbalumọ jia-bale Sturmey-Archer mọ ọ ati pẹlu ina "Dynohub" niwaju ati lẹhin. Ireti enikẹni ti o ba ngun basikulu ni lati ni basikulu iyanu yi pẹlu igberaga. Bere lọwọ onibara basikulu rẹ pe ki o fi Raleigh "Superbe" han ọ.
ANFANI ISURA IRINṢẸ fun ojulowo basikulu ti o ba ni isura dada. Awọn arẹwa ohun isura ni o njẹki Raleigh "Superbe" peye dada, awọn nkan ti o wa pẹlu isura na ni Sturmey-Archer oni jia-bale mẹta ati ina 'Dynohub' onirin-funfun ti o ndan ... Jia Sturmey-Archer njẹki gigun basikulu rọrun ... ni gbogbo agbaiye. Isura irinṣẹ "Dynohub" ... iwaju ati ẹhin bi a ba ti fi owo to ... Tire ... gbogbo iwọnyi pẹlu basikulu Raleigh "Superbe".
Move with the times ON A CYCLE
BASIKULU RALEIGH
oni-gbogbo-ara kiki irin-tutu
Eyiti o jade lati ile-iṣẹ TITO IRINṢẸ Basikulu RALEIGH ATATA Mushin, EKO.

Published by Allied Newspapers Limited, Elephant House, 214 Broad Street, Lagos and printed for them by Amalgamated Press of Nigeria Limited. Fun owo "IROHIN YORUBA" odun kan—Eko sile mejo ati kobo mejo (8/8d.). Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun sile metala (13s.). Olotu S. M. Ademuyiwa, 2 Idumagbo Street, Odi-Olowo, Mushin.